# OKU OJO META DIDE, ALADURA TUKA




SEE YOU PAY THE CORRECT PRICE.



ELETI OFE
A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJO





AWOGBA Omode fun Giri, Eyi, Hiku-ehin, Orere. Ra Tire Ni Ile Egbogi — ISE — Olodumare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St LAGOS



VOL. No. IX 520. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, MAY 18, 1957. KỌBỌ MEJI (2)


## Oku Ojo Meta Dide, Aladura Tuka

IGANDO. Nilu Igaado, awọn ko ntete sinku wọn, nitori nwọn ni lati ṣe eto ibilẹ fun. Obinrin kan ti nwọn npe ni Rachel o si jẹ ọkan pataki ninu ijọ Aladura, o si tun jẹ iyalode Igaado.

Obinrin ti a wi yi, Rachel ti salaisi ni oru mẹja, awọn Aladura nfẹ gbe, awọn Ologboni pẹlu nfẹ gbe oku rẹ. Aladura wa lọ pagbo yi oku na ka nibiti nwọn gbe tẹku rẹ si, awọn ologboni ẹwẹ joko si ẹsọ ita, ẹni kini nleri, ekeji nleri, wipe bi e ba kan ọrọ ti ẹni keji ylo fi gbe oku na, ylo kuku gbe ilẹ ni.

Oku yi ti wa nilẹ to ọjọ meta ti nwọn ko sin. Bi awọn Aladura ti nkọrin "A o pade leti odo", bẹni oku yi ji dide fuyal lẹsẹkanna, o si wipe, eti odo wo ni ẹ npade.

Agbako l ọlọmọ ko duro gbe ọmọ rẹ, ẹlomiran ninu awọn Aladura ko duro mu aṣọ ibori rẹ ti nwọn sare jade, Awọn ologboni ko mọ ohun ti o ṣẹlẹ, ṣugbọn nigbati nwọn ri odidi gende ti o sare jade awọn na paapa, ṣiyan ko duro gba ọbẹ, ẹru ba oku na paapa, o sare jade kuro ninu ile o si gba tẹle wọn lẹhin, Nigbati oju walẹ tan ni oku na dahnu pe, on lọrọ lati sọ.

## Awon Okawe wa niyi





Awọn mejeji ti a nwo ninu aworan yi jẹ awọn ọkawe wa nilẹ Aganyin, ṣugbọn wọn da kan wa wo ile, awọn si fẹ lati wa fi oju ri ile iṣẹ wa. Ẹniti o wa ni apa ọtun ni Nathaniel Ojuọlape, o si jẹ ọmọ ilu Ọgọtun. Ilẹ Aganyin lo fi ṣe ibujoko lati ọdun 1945. Nkan Ogbin lo ti nra fun Oyinbo John Holt ni Ondo ri lẹhin na lo tun bẹrẹ si kiri aṣọ Ṣugbọn iṣẹ Daiyamon wira lo nṣe nisisiyi lẹhin ti ogun Pari tan.

Ẹni keji ni Gabriel Fọlaṣade. Iṣẹ Daiyamon wira ni on na nṣe nisisiyi ni Akim-oda Iṣẹ Onigẹdu lo ti nṣe tẹlẹ ri nilu Twifu. Ọmọ ilu Ada ni on ṣe nilẹ Yoruba.

Nwọn ko tun ni pẹ pada si ẹnu iṣẹ wọn nilẹ Aganyin. Ẹ o bale nire o. Ọkọ ofurufu ni awọn ba de.

## T. A. Thompson



Ẹni ti a nwo ninu aworan yi ni ọgbẹni Taju A. Thompson ti o nṣe olotu agba nibi iṣẹ iwe irohin Eleti-Ọfẹ, O jẹ ọkan ninu awọn Oniwe Irohin Eko ti ijọba fi iwe pe wipe ki nwọn wa tẹti lelẹ gbọ ọrọ ti nwọn fẹ sọ nilu Oyinbo nipa ominira fun ilẹ Nigeria, O ba awọn ẹgbẹ rẹ yoku fo bi ẹiyẹ lọ silu Oyinbo lọjọ Alaruba Ọkọ a re foo, alọbọ ni irin ajo na yio jẹ.

## Oil Prospecting Rights Granted in Bolivia

The Bolivian Government has granted oil prospecting rights over 5,000,000 acres in two separate blocks to Shell Prospecting Company, Limited. This follows the granting in January 1957 to the same Company of a non-exclusive reconnaissance permit over a large area

(Wo yoku lọju ewe kẹjọ)

# Boys Scout's Jamboree



Awon odomokunrin ti o je Scouts ati awon odomobinrin ti o je Guides ti ngbaradi fun ere nla kan ti nwon npe ni Jamboree. Ninu ere yi, ese gbogbo awon Scouts lati awon ilu ti o nso ede Gesi ni yio pe nibe, ti olukuluku yio ma da ara ati ere ti o ba fe ti awon yoku yio pe le lori, awon o ma woran.

Ninu aworan yi, e ko ha ri awon Scouts okunrin ati awon Guides obinrin ti nwon njo ni ibudo won ti Eko ni Makoko?

awon ma san lori emu poju. Ki won jowo ba won wo se.

Orin ti won ako nijona bi won ti nlo niyi:

"Omo Akinyele tete da wa lohun o, Owo logun obinrin.

Akinyele, se iwo na si a nwa".

Nigbati won de odo oba Akinyele, won ba Oyinbo ajele kan nibe, iyen na ba won da si oro na. Oni nkan ti o ba ndun won lokan ki won ko sinu iwe ranse si igbimo ilu Ibadan awon yio si ba won fi egun otolo to oro na dada.

Ayiluka Eleti-Ofe gbo wipe edun awon alemu wonyi nipa owo ti ijoba bu si emu ti poju oro sile marun se diedie o di poun kan lowo enikokan. Ati pelu nkan ti ijoba Ibadan (Ibadan District Council) se silu ti won fi nbu owo lu gbogbo nkan ko ye awon si.

## Odun Easter Isisiyi Ko Dun Bi Ti Ojo Igbani

A gbo lenu awon alagba wipe, bi oju ba ti nla siwaju, beni ohun gbogbo yio ma dara siwaju, sugbon kaka ki nkan dara siwaju laiye isisiyi o dabi eni wipe nse lo mbaje.

Nigbati awon Kiriyo pataki pataki si wa lori ile, die ninu awon enia bi Capt. Davies Parati (Pratt) Ayibi Williams, George Orloye, Y. St A Ariori, Payne, Henry Car, Chris Sapara, Sybygle, Makoli, Faidal Cole Biggs:es, Layeni, Adesigbin, Lumpkin Bukloe, Kester Jeje Sule Alapoti, S. Thomas, Ogunbiyi melo ni ao daruko tan. Bi odun Easter ba mbo bayi, kuku-keke awon nigbana yio jeki esin Kiriyo wu enia lati se.

Ni owuro ojo Easter Monday, olukuluku awon awon omo Kiriyo ti o ti mura sile lati ojo Sunday, yio ma ro kiti-kiti lo si Oyingbo Oke odo tabi Oyingbo ni a ti npe ri sugbon Kiriyo nwonyi lo nfi ede Oyinbo pe e bayi pe Mo nlo si Abutement". awon ti ko kawe lo npe ni Ebutemeta eyiti o di oruko ti a fi npe e loni.

Nwon o ma towo lo si Oke-Odo, lona Yaba, ona Sango, ona Ago Egba, ona Oke Baba, sugbon awon ti o nlo si apa ona Ijero lo poju, olukuluku pelu ilu ati Ifon ti nwon o si gbe Gudasi ro.

Eniti nwon ba sere fun ti oluwa re si fun won lowo nigbana ni nwon o so Gudasi kale, awon ti o mu apola igi dani Kondo, Kumo nwon o bere si lu Gudasi pelu orin bayi pe:-

Gudasi ! ole !
Gudasi, Ole !
O pa Jesu je Ole.

Nigbati agogo merin irole ba ti lu, ni gbogbo awon ti o ti lo lati owuro yio bere si dari wa sile. Nigba na gbogbo awon ara Eko, ati Kiriyo ati Imale ni yio gbe apoti lati joko si egbe opopo Victoria lati wa pade awon ti o ti lo lati owuro, lati wo iru aso ti awon ro.

Ohun ti o tun se pataki ti nwon nse nigbana ni wipe nigbati nwon ba mbo wa sile orisirisi eso igi ni iwo yio mari lowo awon omolodun nwonyi bi eso awin, Mongoro, Olowun, Oro, Kaju, Kantanyan. Igba. Goroba ati opo eso bawonnni. Sugbon lati odun 1930, gbogbo asa wonyi ti yipada si bamiran.

## Awon Elemu Ibadan Fadakori

IBADAN. Ni ojo 'eru ti o koja lo yi gongo so nilu Oluyole nigbati gbogbo awon obinrin elemu ilu Ibadan lo sode lai mu iborun sori - ewe ni won fi se iborun nijona, ni won ba gba ile Olubadan Oba Akinyele lo wipe owo ti won ni ki

## Awon Jamani Yan Ogagun

A gbo irohin wipe awon ara ile Jamani ti o mbe ni apa iwo orun nfi dandan le fun awon Gesi wipe, etu oloro ti nwon nfi agba ibon yin, ki nwon fi ona re na won lowo lati fi se okan ninu ohun idabo bo ile won nigbati ogun ba tun de (Atomic Canna

Asiwaju awon ara ile Jamani ti a npe ni Adenauer so wipe Ogagun Adolf Heusinger ni Adele tabi asoju Adolf Hitler nigba aiye re on yi na ni eniti o ye ki nwon fi se ogagun fun awon omo ogun ile Jamani

Nigbati awon ara ile Jamani ti apa Iwo orun gbo wipe, awon ti fi ona bi a ti se nlo etu Oloro Atomic han awon omo ogun won, idagiri mu won sugbon nwon fi awon enia na lokan bale wipe ko si ewu.

## Gbogbo Pataki Obinrin Ko Koja Okunrin.

OLOTU. Ninu gbogbo ohun ti obinrin le je nile aiye yi, ko koja ti wipe ki o le niyi loju awon okunrin. Orisi iru awon obinrin be je meji.

(a). Nigba gbogbo ni awon obinrin fe ki nwon ni iyi niwaju awon okunrin, nitori idi eyi, awon o ro dede-nwon o gba dede, ki ewa won le yo, ki okunrin ti o ba ri won, ki ori re le wu, Onje ti nwon nje, nitori okunrin ni bakanna, bi awon ba jeun ara won yio dan, tobe ti ewa won yio yo, ti oju okunrin yio si fi mawonwon-

(b). Awon orisi keji wa ti o je wipe, nwon korira awon okunrin tobe ti o fi je wipe bi ko ba si oro ti omo-elomiran ko ke lati tilekun mo ara re ki o mase ri okunrin mo

Loju temi, gbogbo, gule-gule obinrin ko koja okunrin.

## Ogbon Lo Se Wa Owo

IBADAN. A gbo irohin wipe, obinrin kan ara Owerri ti a npe ni Ego ni awon olopa mu ejo re wa han awon adajo ni Kotu Bere wipe, o so ile re di ile agbere.

Awon olopa so wipe obinrin yi nitoripe o ti di arugbo awon okunrin ko si npe mo wa lo silu re Owerri lo mu odomobinrin wundia kan bo.

Bi o ba ife fi omu wundia na sere nikan ni iwo yio san sile meji abo. Bi o ba si nfe gbonmi si mojo ote ni owo re.

Adajo ro oro obinrin na siwa sehin o si ri pe o jebi, o ni ki o lo san Poun mejo tabi ewon osu meta.

## Idahun Si Ibere Otun

Olotu,

Gba mi laye lati dahun si ibere Ogbeni S. Otun nipa, ariwo ti awon omo ile Kewu npa, nigbati nwon ba nkewu ti awon omo ilewe si npa roro.

Mo fe lati fi ye Ogbeni na pe, asa ilu eni yato si ti ilu miran. Ranti pe bi agbalagba ba ran omode nise, nwon o so fun omo na pe, nse ni ki o ma fi oro na korin niso ki o ma ba gbagbe.

Nigbati omode ba ntenu mo ohun kan nigba gbogbo si etigbo ara re ko ni gbagbe nkan na boro.

Asa yi na ni awon Oluko nko nigbati nwon ba nwi fun omo akeko wipe "E tun tun wi, ako gbo".

Idi keji ni wipe bi omode ba joko iseju marun ti ko se ohun kan yio bere si sun sugbon nigbati nwon ba ri gila-gila ti nwon si bere si kewu eyiti o dabi wipe nwon npariwo, nse ni oran sisun yio salo.

Emi ni

Lemomu Ajakuta

## Awon Jagun-jagun Olokiki Nile Enia Dudu

Ninu awon jagun-jagun ti o lokiki ti a si gbo irohin won bi nwon ti se gudugudu meje die ninu oruko won niwonyi.

Afonja ni ile Ilorin, Kosoko ni ile Eko, Adamu ni Ilorin, Ogedengbe ni Ilesha, Ajofero ni ile Imesi Oloja-Oke, Ibikunle Oloke, Ogunmola Are latosa, Ajayi Ogberi-efon sa fiiafila, ni ile Ibadan, Ajalaiye, ati Ajalorun nile Ife, Lisabi, Oke-nla, Akodu, Ogongo-nifila, Ogundipe Abowaba nile Abeokuta, Akindobire L'Ondo, Ajamgbile ni Bini, Eyinle ni Ilobu.


HINDU SANKARA'S
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

*Enclose 4/- money order by Air Mail for Catalogues and Literature.*

HINDU SANKARA, 20 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England



**Kere o!**

A ti ni origirisi ogun German to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos.


## Omoba Gesi dan ise awako wo



Awon omoba ilu Gesi, Charles ati Anne lo se ibewo awon oko reluwe kekeke ti a npe ni Romini, Hyse ati Dymsosi Awon omoba na fi ola baba ati iya won woko reluwe lati Romini si Hyse, o je buso mesan.

Eni ti a nwo ninu aworan yi omoba Charles ti o sise pana-pana ninu oko reluwe kekere na, sugbon nigba gbogbo ilo nfi fere oko na sise.

Kole se ki o ma ya, a gbo wipe baba re na ti se ba ri.

ELETI ỌFE
A-NIU-WỌN KO SE WI L'BJO
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
18, Kosoko Street, Lagos "ELETI - OFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL IX. NO. 520. LAGOS, SATURDAY MAY 18. 1957

# E Jeki A Gbadura Fun Won

Nisisiyi ti gbogbo awọn Oṣelu wa jake-jado ti ba ọkọ lọ silu Oyinbo lati lọ ko ire oko wa sile fun wa, o wa di iṣẹ temi ati tirẹ ati oyun inu pelu lati kun fun adura, fun awọn oṣelu wa na jake-jado nilẹ Nigeria, ki Ọlọrun le ran wọn lọwọ ki nwọn le yanri ohun ti nwọn ba lọ si rere. ki o ma si ṣe si edekoyede rara. larin wọn.

Ati wipe ki o maṣe si alawigbọ. ki ete ati ero wọn si jẹ ọkan. Nigbati a ba ngbadura yi yala Kiriyo ni tabi Musulumi, Onifa tabi Onisango, ki a ma gba a lọsan ati loru, fun ilọsiwaju ile wa.



# Awolowo Nile India

Awọn ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọlọla Oloye Awolọwọ on pẹlu Oloye Akinloye ti o nṣe Minister fun ilọsiwaju iṣẹ agbẹ ni agbegbe Iwọ-Orun Nigeria awọn mba Nehru sọrọ nipa ohun ti o le mu ilọsiwaju wa fun ilẹ wa gẹgẹbi orilẹ ede ninu irin ajo rẹ ti akọkọ.

Nisisiyi aṣiwaju wa yi ti tun fi ori la okun la ọsa lọ silu Oyinbo fun anfani emi ati irẹ alọ re, abọ re, alọbọ ni ki irin ajo ti ẹkeji yi na tun jọ.

# …won Babalawo Fe Se Etutu

Gbogbo awọn awujọ Babalawo kakiri ilẹ Yoruba ati ni agbegbe Ilọrin ylo ṣe etutu leri ọrọ ti nwọn lọ sọ nilu Oyinbo, ki abọ rẹ le dara, ki o si suwọn.

Asiko ti nwọn fi ọjọ etutu na si ni akoko igba ti nwọn o ṣe ọdun Ipele eyi ti awọn baba wa ma nṣe lasiko ti akan eleso bẹrẹ si so. ọjọ na si bọ si ọjọ 15th oṣu May 1957.

Ni asiko etutu na, nwọn o wure fun ilẹ Yoruba (Western Region) wipe ki o le gba ominira lọdun ni, ki apapọ ilẹ Nigeria le gba ominira ni ọdun 1959.

Ki Edumare ṣe atọna awọn ikọ gbogbo ti o lọ ṣe eto na nilu Oyinbo, ki alọ wọn dara, ki abọ wọn si layọgidigidi.

# Baba - Sango wo Sosi, O Di Pe e Nauka

IBADAN. Lọjọ Easter Sunday ti gbogbo ijọ na nkọrin wipe "Kristi Oluwa ji loni, Haliluya." Awọn Akọrin nhan bi ẹiyẹ ibaka, Aladuru, atẹ duru, gbogbo awọn ijọ le gbe ohun orin soke, ti ọpọ awọn en'a nwo oju orun.

(Wo iyoku loju ewe karun)



# Awon Enia Mejo Binu Jade



Ogbeni yi, Harold Memillan to nse Prime Minister ti ilu Gesi on lo so fun awon igbimo nilu Oyinbo wipe owo ti awon yio san fun ilu Egypt fun oko Gesi ti o lo odo Suez, nwon o san a si inu Bank. Nigbati igbimo gbo awon enia mejidilegun pe ara won jo, akehin si re ni pe awon igbimo mejo binu wipe, awon ko lowo ninu ero be, nwon si binu jade lo,

## Aboke Karele Ori Oye Yi Sode O!

IBADAN A gbọ irohin wipe Iyafin Bamgbọpa ti nwọn npe ni Iya Okebukọla ti nṣe Abọke nilu Ibadan ṣalaisi ni gẹrẹ ti nwọn bọ Oke Ibadan pari.

Abọke yi ku sinu ile rẹ ni kotu Bẹrẹ, ati pe ọjọ ori rẹ to mejile-lọgọrun, ninu ọdun 1855 ni a bi ati wipe on ni Abọke kẹta lẹhin ti a tẹ ilu Ibadan do.

Ninu oṣu June ni nwọn o ṣe ọdun egungun ni Ibadan a si gbọ nibi to dọṣọ pe laseko na ni nwọn ma fi Abọke miran jẹ.

Nigbati nwọn nṣe ti oku iya na Orin yi ni agbọ ti nwọn nkọ.

Iya ka ,rele Ori oye yi si o de o Boba ṣe ya ẹlomiran loku o A ṣe wẹ-wẹ a dakẹ o Ki lo pa dan? Omi Ajalolo.

## Jamba Se Moto Kan Ni Abidjan

ABIDJAN. A gbọ irohin kan wipe mọto kan ti o nlọ si ilu Abidjan pẹlu ọpọlọpọ awọn ero ninu ọkọ, lo ṣẹṣi lọ fi ori sọ igi o run womu-womu, tobẹ ti iwọn ọgbọn enia fi ni lati fi ara gbalamọ ati wipe nṣe ni mọto na kọja nkan ti enia atuaṣe. A gbọ wipe gbogbo awọn ti o fi ara ṣeṣe yi wa ni ile alaisan.

# Awolowo de ilu Oyinbo

Ni wara nṣeṣa ti Awolọwọ de ilu Oyinbo nṣe ni awọn onifọto da oporo foto yiya bo o, awọn oniwe irohin si bere lọwọ rẹ wipe owo ni ero rẹ ni wọn igbati o je wipe agbegbe Iwọ-orun nibiti o gbe jẹ oye Premier lo ni owo lọwọ ju awọn agbegbe yoku lọ?.



Oloye Awolọwọ dahun pe, ki a tilẹ pa ti owo aini ti sẹgbẹ kan. Bi awọn agbegbe mẹtẹta ba le fi imọ ṣọkan pọ nigbana ni ilẹ Nigeria yio te di alagbara

Ogidi - aleje awọn enia leyinbo ati lenia dudu lo wa pade Oloye Awolọwọ ninu wọn ni Alaye luwa ọba Ọni ile Ifẹ, Oloye Rotimi Williams, oloye Okorodudu, Matthew Mbu ati Alhadji Abudu Maliki aṣoju ilẹ Hausa nilu Oyinbo.

Nigbati awọn ọmọ Yoruba te mbẹ ni ilu Oyinbo mbọ wa pade oloye Awolọwọ awọn obinrin inu wọn ro aṣọ kanna, awọn ọkunrin wọn wọ aṣọ ilẹ Yoruba, awọn si bẹrẹ si jo Konkoma ati Agidigbo lọ pade rẹ orukọ awọn eniju ti o lu ilu fun wọn njẹ Ambrose Campbell Band.

A gbọ wipe awọn Oniwe-rohin fẹ ki o wa ba wọn sọrọ ṣugbọn ko gba fun wọn. Ṣugbọn o sọ fun wọn pe, eto nipa ominira ti nwọn titori rẹ wa silu Oyinbo, lọtẹyi, ko ni dabi eyi ti nwọn ti nṣe tẹlẹ ri bi iru ti 1953 kọ ati wipe ẹmi iṣọkan ti o mbẹ ni ilẹ Nigeria nisisiyi, yio jẹki ọrọrun fun ijọba Gẹsi lati fun wa ni ominira ni ọdun 1959 ati wipe tabi-tabi ko si, ijọba agbegbe Iwọ-orun ati ti Ila-orun ni lati gba ominira lọdunni.

Awolọwọ sọ wipe, ninu gbogbo ipade ti nwọn ti nṣe nilu Oyinbo, eyiti nwọn o ṣe lọtẹ, o daju pe nkan yio ṣẹnu re jọjọ on si rope, ọrọ ti nwọn fẹ sọ yi, nibẹ ni ao ti ri oye nipa ominira wa.

Oloye Okorodudu dahun wipe lati fi han bi ipade ọtẹ yi yio ti larinrin to, gbogbo awọn aṣoju agbekọkan lo wa si hin pẹlu ayọ lati wa pade Oloye Awolọwọ, iru eyiti ko ṣe ri.

Nwọn fiwe ranṣẹ si Awolọwọ wipe ki o wa sọrọ sinu ẹrọ asọrọ-magbesi vio lọ ba awọn ọmọ akẹkọ ti Oxford sọrọ bakan na ni yio tun lọ ba ti Cambridge sọ pẹlu, yio si tun ba awọn ọmọ Yoruba sọrọ diẹ.

## Baba Sango Wo Sosi O Di Pe e Ntuka

(O bẹrẹ loju ewe kẹrin)

Bi nwọn ti nkorin yi lọwọ, bẹni Baba-Ṣango kan, ti o nyọ ina lẹnu, leti ati ni imu ba ya hara sinu Ṣọsi pẹlu awọn Iya Ṣango ti oriṣa ti gun gbogbo wọn. O di pe e ntuka ati Alufa, ati Akọrin, ati Aludaru ati Katikisti oju ferese ni nwọn fi ba jade. awọn ero ijọ wa di aṣubulebu.

Ni gẹrẹ ti nkan yi ṣẹlẹ ni awọn ọlọpa 99, gbe mọto de ti nwọn si ra Baba Ṣango na mu, o mbẹ ni ipamọ nisisiyi lọdọ awọn ọlọpa pẹlu Ṣango ori rẹ ti o nmi.

# Mallam Adamu d'ologbe



Ogbeni Hausa kan, eni ti a npe ni Malam Adamu ti a gbo pe o je okan ninu egbe N.P.C. eyi ti Sardauna Sokoto ti a nwo ninu aworan yi je asiwaju fun, Salaisi nilu Bini.

A fi eyiyi ki Alhadji Ahmed Sardauna Sokoto pe o ku afeku.


IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ ewa ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma mba ọmode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun ọmo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

ỌMỌRELA BABY MIXTURE

(SILE MEJI ABO TOLA, FUN IGO KAN)

O wa Lọdọ —

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS


# Isipaya nipa arun Jedi - jedi

Jẹdi-jẹdi jẹ arun kan ti o buru jọjọ ti ima ba tọkunrin tobinrin ja, ko si ẹniti arun na ko mba ja. Arun yi buru to bẹgẹ ti o fi jẹ wipe, ẹniti arun na ba pọju lara rẹ ko ni le ṣe bi ọkunrin, o si ma njẹki idi ẹni yọ Irobo sode,

Ohun ti o nfa arun yi wa ni wipe, bi enia ba njẹ adun pupọ, a ma jẹki arun yi tunbọ gbojikan lara enia. Ki nṣe nkan didun ni kan lo nfa arun na wa. Ẹgusi ni jijẹ pupọ a ma fa a, Ẹpa tabi ororo ni jijẹ pupọ a ma le arun na loro.

Arun jẹdi-jẹdi a ma fa Igbẹ-ọrin, airi igbẹ ya, Ki enia ma yagbẹ ẹjẹ, tabi ki idi ma rin enia winni-winni. Ko si ẹniti a bi ti ko ni arun jẹdi-jẹdi lara Ogidinlẹje awọn enia ni arun yi ti padanu, ṣugbọn awọn ọmọ ọwọ ni arun na papọju.

Ọpọlọpọ awọn enia lo ti fi Iwa ọmọ mi ikẹ ọmọ mi igẹ pa ọmọ wọn danu nigbati arun yi ba nyọ ọmọ wọn lẹnu. ti ọmọ na si wa bẹrẹ si yọnu, kaka ki nwọn ṣe akiyesi ohun ti o fa idi kike ọmọ na, nwọn o ma ra nkan adidun fun, ṣugbọn awọn obinrin ti o gbọn, a ma fi omi gbona rọ idi ọmọ na nwọn o si tun ma fun ni agbo nu. Ọlọrun ko maṣe jẹki agba tan lorilẹ.

# Awon Egungun meji ba ara won ja

Lasiko ti nwọn nṣe ọdun Egungun ni ilu awọn Igbira, awọn meji kan pade ara wọn ti o jẹ wipe totun tosi awọn Egungun na lo ko awọn jinduku sẹhin.

Ekini kọ lati yago lọna fun ekeji kọja, awọn mejeji si nkọrin Agan bi ekini ti ntu apo, bẹni ekeji ntu ado, Agbarc-gbabọ, awọn Egungun mejeji lo kọkọ bẹrẹ ija. Ekini nkọrin bayi pe "Tọlọmọ kan lo ṣoro, konko lawa ṣoju" ekeji ẹwẹ si bẹrẹ si kọ orin bayi :"Bo le dogun ko dogun, bo le d'ọdẹ ko d'ọdẹ, ojo p'ewe koko, bo le ya ko ya"

Lẹifa ọrọ gun, ijagbero bẹrẹ larin awọn egungun mejeji, ati pe, bi ko ba si ọpẹlọpẹ ti awọn Ọlọpa boya nṣe ni ọrọ na iba di ogun ti yio fọ ilu Igbira ọpọlọpọ awọn enia lo fi ara gba ninu ija na nṣe ni ile alaisan kun fọfọ. Tabi kini a ti npe iru eyiyi si, a ha le ṣe ajọdun ki a si gba ibẹ yọ si ọrun bi ?.

# Alufa Yakubu Tako Adamu

EKO A gbọ irohin bi Alufa Adamu ti sọ wipe, sẹgẹbi Ọba Adele keji ti jẹ ọba, ko si ẹtọ kan lati ṣe ẹnu fun awọn ara Eko lori bi nwọn ti fẹ ki ilu wọn jẹ.

Ibẹ ni Alufa Kafo Yakubu ti o nṣe akọwe fun awọn ẹgbẹ Lagos Muslim Youth League dahun pe, o n ṣẹgẹbi Alfa, o n lodi si ọrọ ti Alufa Adamu sọ.

Niteripe ni ọdun 1947 Ologbe ọba Falolu ṣe ẹnu fun awọn ara Eko nigbati awọn ẹgbẹ N.C.N.C. ṣe ikede nigbati nwọn fẹ lọ silu Oyinbo.

Niwọn igbati ọba igbana ti le ṣẹnu fun awọn ara Eko eṣe ti ọba isisiyi ko fi ni le ṣẹnu fun awọn ara Eko. Ọba Adele ni ẹtọ lati sọ bi o ti fẹ ki ilu re jẹ. Ọwọ ẹni la ṣa fi atun iwa ẹni ṣe.


Polewo oja re sinu iwe irohin Eleti - Ofe

# Awon moto to sese de



Gegebi a ti so wipe ili ojojumo ni orisirisi awon moto nde si, Eko gbogbo awon orisi moto ti a nwo lo janrere nwonyi, oko oyinbo ti o duro yi lo ko w o n guule si ebute Apapa. Nitorina ijafara lewu, oju ona ti moto nrin ko fere ju gegebi o ti wa lo ile Nigeria n i gbogbo re wa oko ti o duro na, ko ko nkan meji a fi eru moto. Gbogbo awon oko ti o si nde si Eko, ko si eyiti ko nwa moto bi mewa gunle lojumo kan.

# Ladele Ogunmola Ko Omo Jade

Ese k o gbeli n i I t a Akanni, nigbati Olori awọn Oniburedi Ọgbẹni Ọladele Ogunmọla fi ko omọ omọ rẹ jade, ero p o b i omi, orisirisi awọn ẹgbẹ lo ran aṣoju wa si b ẹ lati i l u Awẹ.

Abọsẹde ni oruko iya tuntulu yi, o dun wo la rin awọn ẹgbẹ rẹ, o kori rẹ gẹgẹbi ti oloyinbo, nṣe ni awọn ẹgbẹ ọkọ rẹda oporo owo bo o.

Diẹ ninu awọn muju-muwa ati gbajumu ti o wa nibi I k o m ọ na n i Ọgbẹni Oyetunde, ti o nṣe ọmọ Balẹ ilu Awẹ, E.O. Amọjẹ A Ṣowọle Ẹkerin, L.-Ọlasanmidele D. Ogundele, Z, Ọ j e d e l e Z. Ọlaọsun, J.M. Babalọla, S.A. Abudu O Ọdẹbiyi.

Awọn ẹgbẹ ti o wa nibẹ niwọnyi Ẹ g b ẹ Ṣebotimọ Ẹgbẹ Garu, Ẹgbẹ Ọrẹpeju No. 1 ati No. 2, Ẹgbẹ Mabọreje, Idowu Baniya

Diẹ ninu awọn obinrin ti o nawo nọra nibi Ikomọ na ni Iyafin M Ogunmọla, O Lawọyin ati I Ogunmọla

SIR JOHN MACHERSON



Aworan yi niti Ọgbẹni Sir John Macpherson, ti o kọkọ joye Governor - General nilu Eko, nisisiyi o ti di akowe igbakeji Sekiteri agba nilu Oyinbo o mbẹ ninu awọn ti o lọ pade Oloye A w o l ọ w ọ nigbati o gunlẹ silu Oyinbo.

# Akinpelu Obisesan



Aworan yi ni ti O l o y e Akinpẹlu Obisẹsan ti o nṣe alaga awọn ẹgbẹ Powọpọ ilu Ibadan o si jẹ ọkan pataki ninu awọn ẹgbẹ agbẹ Onikoko, ati pe Oko koko rẹ pọ jọjọ, bakanna lo si jẹ ọkan ninu igbimọ awọn Oni koko Marketing & Export.

# Awon Ilorin da oluko duro

ILỌRIN A g b ọ w i p e awọn ijọba ilu Ilọrin ti da awọn ọ g a ilewe m ẹ t a duro lẹnu iṣẹ nitori owo ile iwe ti o pora l ọ w ọ w ọ n ni aipẹ yi. Orukọ awọn arakunrin n a niyi: Amos Abidoye t i ilewe Malete Malamu A d i s a Bọlanta,, ti ilewe Bodesadu a t i Malamu Y e s u f u Marafa olori ilewe Afọn.

A w ọ n agba ogbogan mẹta ni ilu ni ki w ọ n yẹ ọrọ w ọ n wo nigbati wọn gbọ pe nkan ko lọ dede nilewe wọn mọ, atipe gbogbo owo ti a ni lati lo fun ilọsiwaju ẹ k ọ ni wọn ti tẹri.

Awọn ọlọpa si nro ọrọ wọn wo bi awọn yio b a wọn se ẹjọ.



## ARADAN NERVIGORA

Ogun ẹjẹ pataki fun imarale agba ati arẹmọ pipe fun awọn alaya pupọ. O dara fun inarun, ẹjẹ dudu, iṣokun oju, gbigbọn ọwọ, ailesun, ailokun ninu, ati irufẹ arun bawọnni. O jẹ ajidewe fun awọn ti agbara wọn ndinku. On na gan ni ọkunrin yi lo ti o fi di "Afẹsẹ kun bi ojo." 5/6d. pere pẹlu owo ọkọ 1/6d e.g. 7/- Post Free.

**The Egba Trading Aradan Stores**
112, Denton Street, 18, Denton Bridge Street, P. O. Box 2. Ebute - Metta.
Phone 44153. A tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.

## Ẹnyin agbe esu de Nigeria

Ozan tiarọ ba ti gbọ tẹlẹ wipe o mbọ, o daju pe ko ni pa arọ.

Nitoba gbogbo ni a nṣe kede fun nyin wipe eṣu mbọ, iba ti wipe koiti de ilẹ Yoruba ni kan lo ku nṣe lo nja ilẹ Hausa logun nisisiyi.

Nibi nwọnyi Asare, Katagun, ati ni Bauṣi nṣe ni awọn eṣu ja wọn logun ninu oko wọn gbogbo ewe agbado, Dawa, Ọka-baba, Jero, Alikama Ọka-Bale ati Ireke ni wọn bajẹ.

A tilẹ gbọ pe nṣe ni Oyinbo Ajẹlẹ nṣare kakiri ninu oko iresi. Ẹnyin agbẹ ẹ ma gbaradi.

**Overforty Tonic**

A REJUVENATOR TONIC AND BLOOD PURIFIER
For growing men & women
4s 6d
ANJORIN CHEMISTS Ltd.
116, King George Avenue, Yaba and Branches, Phone 44288.

## OIL PROSPECTING RIGHTS GRANTED IN BOLIVIA

(Obẹrẹ loju ewe Kini)

of the country. The two new blocks which are of about 3,700,000 and 1,300,000 acres respectively are situated in central Bolivia.

Preparations are already in hand to start aerial survey, surface geological and geophysical work.

No. 66.

# Federal Government Scholarship Scheme 1957 - 58

A large number of applications has been received in response to the Government Notice No. 2183 in the Federation of Nigeria Gazett of 6th December, 1956, and subsequent similar notices advertising the Federal Government Scholarship award to be made in 1957. Naturally candidates prefer to choose their own careers and course of Study but their choice may conflict, in some cases with the Government's Scholarship policy to provide grants to assist Nigerians in qualifying for Government posts. This year's applications to meet the need of certain Federal Department.

2. Awards of Federal Scholarships must be related as closely as possible to the needs of Government Departments, and of the Country in general, and applicants who fail to secure the Scholarship of their choice may be asked to accept a scholarship for other courses for which their qualifications fit them. A number of awards is likely to be reserved this year for courses of study leading to a professional qualification or an Honours Degree in Engineering, Mathematics, Forestry, Botany, Zoology, Geology, Chemistry and Physics, and Veterinary Science. These qualifications are required for senior posts in the posts and Telegraphs, Public Works, Civil Aviation, Education, Geological Survey, Meteorology, Veterinary Research, Agricultural Research, Land Chemistry and Survey Department.

3. Applicants who have already been invited to an interview before the Federal Scholarships Advisory Board, and who wish to be considered for courses other than those for which they have applied, are advised to make their wishes known at the interview, or in writing as quickly as possible by sending a letter to the Secretary, Federal Scholarships Advisory Board, Ministry of Social Services, Lagos.

**E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Fun Irohin Aladun Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re**



**Nje nwon fe gba bolu lose yi? fi egbogi ajebidan pa awon ibiti o ndun o**

**ELECTRIC Balm**



## ILE MBE FUN TITA NI Suru - Lere LATI £1250 SI £1600

Ẹniti o ba fẹ le ra awọn ile na ni daalẹ tabi ki o ma da owo rẹ san diẹdiẹ bayi :-

Ẹniti o ba ra ile oni adọta le lẹgbẹfa Pọun (£1250) yio san asansilẹ adọta-lerugba Pọun (£250).
Ẹniti o ba ra ile ẹlẹgbẹjọ Pọun (£1 600) yio san asansilẹ irinwo Pọun (£400)
Olawa rẹ ni lati san owo ti o ṣẹku tan larin ọdun mẹdogun (15 years)
Ẹniti owo tirẹ ba ṣẹku ẹgbẹrun Pọun (£1000) yio ma da san ni Pọun mẹwa-mẹwa. (£10) loṣoṣu
Ẹniti owo tirẹ ba ṣẹku ẹgbẹfa Pọun (£1200) yio ma da san ni Pọun mejila ati ṣile kan (£12 1/-) loṣoṣu.

Wọn o kọ gbogbo awọn ile na ni abẹ abojuto igbimọ L.E.D.B.

Ẹ kọ kọ kọwe si:-
NIGERIA BUILDING SOCIETY
5, Customs Street
P.M.B. 2078
Lagos

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company. 28, Kosoko Street P. Box O. 467 Lagos Phone 2337